The Chief Secretary to the Govt

Ọrọ Iwe Ipingun Ọgbẹni W. R. Harding Ologbe mbẹ ninu " Eko Akete t'oni.

# EKO AKETE.

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI."—W. T. STEAD.

VOL. VI. No. 267. SATURDAY, MARCH 24, 1928. 4d.

The Leading Weekly Vernacular Newspaper in Nigeria.

NIGER... 29 MAR 1928

## *White's Radical Gonkiller.*

:o:

(NATIVE.)

[ *A complete cure for old and fresh Gonorrhoea.* ]

When Gonorrhea is not properly cured, it gives rise to other troubles and diseases, such as Barreness, Piles, Kidney Diseases, Stricture, Rupture, Rheumatism, Sore-eyes, etc.

**N.B.**—This Medicine cures Gonorrhea completely in either man or woman, so that no secondary diseases can follow.

Made from pure **Native Herbs,** and sold only by

VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist.*

41, Offin Road, Lagos.

PRICE: Ten Shillings (10/-) per bottle.

*Packing and Postage 2/6d. extra, to all parts of Nigeria.*

---

EGBOGI ALAWOTAN ATỌSI.

:o:

[ *Fun Atọsi lailai ati titun.* ]

Ti a ko ba tete wo Atọsi san daradara, o ma ndi enia lọwọ lati ṣe abiamọ, o si ma nfa oriṣi arun mi wa, bi:—Jẹdi-jẹdi, Aran, Iju, Ẹda, Ipake, Ase, Lakuregbe, Arun Oju, ati arun mi.

*N.B.*—Egbogi yi nwo Atọsi san lawotan patapata, lo si nję ki o ri aye wu arun mi silę.

"AWA O MA JO, AWA O MA YỌ, NI"

Aga ati Asia (*Flags*) ti Germany lorişirişi wa fun hihaya ni No. 3, Docemo Street, Lagos. Aga ati Asia wọnyi dara fun akẹkẹyẹyẹ pupọ, fun Igbeyawo Wolimọ, Ijọ-Ọdun Musulumi, tabi ti Kiriyo, fun ere nile Ẹgbẹ, ati orişirişi ohun ayọ miran.

*Terms very moderate*

for particulars, please apply at :—

EKO-ATORO CHAIRS & FLAGS SUPPLY

*Office* :—

No. 3, Docemo Street,
P.O. Box No. 505.
Lagos, Nigeria.

**Coffins to suit your Taste.**

Coffins with Pillows, Shroud, Brass Edges, and Removable Lids, on sale at J. B. da Silva, 40, Odunlami Street, Lagos: also Gramophone Records, Gas-lamps, etc., etc.

Prices to suit you. No worry, prompt attendance. Make a call.

## Ero ya wa ra

ADEBOYE ṢOLANKẸ Onişowo "Gbabiọgẹdẹ" nta Panu-kikọle ati kikankọ, Işo lorişirişi, Kọkọrọ (Işika) t'ilẹkun ati t'apoti lorişirişi, Atupa fifalọwọ, Simẹnti, Ọda lorişirişi ati Epo-ọda, Fikifiki, Okun ẹrọ, ati Ọşan, ati Pakun ti Awo-ẹja lorişirişi, Awo ti awọn Aganyin fi nko Ẹja-şawa l'okun ati Eja Abọmafọ, ni Şọbu rẹ ni No. 4, Idunmagbo Street, (l'ebute Ọlowu) ati ni No. 19, Moloney Bridge Street, (l'Anikantamọ) l'Eko.

O nta Iworo (Golu) ati Fadaka-tutu ati Irin-işẹ Agbẹdẹ Iworo ati Fadaka.

**Owo Ọja rẹ fanimọra. Ẹ lọ ra tiyin nibẹ.**

**Are you a Mechanic ?—If so you must want Tools, now or soon!**

**Do you intend to put up a house ?—** Then you will require Builder's Hardware!

In either case you cannot do better than call at

**B. C. Vaughan's "Excelsior" Stores**

at Agarawu Street, Lagos.

Where the largest and most varied assortment of Artisan's Tools and Building Materials in Lagos is stocked.

Quality to satisfy all demands, and prices to suit all pockets.

*Special discount to Traders and Wholesale buyers.*

**J. C. VAUGHAN**

Ti ile ọja Sheffield ni ita Kakawa ati ile-ọja *Excelsior* ni ita Agarawu ni orişirişi ati onirun ohun kikọ 'le fun tita ni owo-ọpọku-ọyọku.

Ilẹkun awọn ile-owo mejeji wọnyi şi silẹ fun awọn Ọmọle ati awọn Gbẹnagbẹna: bi o fẹ di awo ni o, ero-ija dida'wo ko ni jẹ ọ ni'ya lati ra nibẹ:

Alagbẹdẹ Wura tabi ti Fadaka ni ọ ni o, gbogbo l'oşe fun ọ lati re yan irin-işẹ tirẹ nibẹ ba kanna.

Owo Ọgbẹni J. C. Vaughan ti di Owo Atọ Ajanaku lọjọ to ti pẹ: bi Ọgẹdẹ si ni Owo rẹ ngbo kakiri ibikibi. Agbẹ ni ọ kai! bi o ri orişirişi Ọja ti o ri ra nibẹ ha yio şe ọ.

Sure tete iwọ Ọmọle, iwọ Gbẹnagbẹna, iwọ Aranbata, iwọ Asenjẹ iwọ Ageginigbo (*Sawyer*) Alagbẹdẹ Wura, iwọ Alagbẹdẹ Fadaka, iwọ Agbẹ re ba ori're tirẹ pade nibẹ.

**Owo-lọwọ ni gbogbo ọja meremere ibẹ.**

*Editor & Proprietor :—*
ADEOYE DENIGA,
*Office* 24, Williams Street,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oșu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oșu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranșẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

ADIGOGORO-WO, ORUKỌ T'A PE IKU !!!

Bi ọmọkọnrin kan ninu awọn ti o nșișẹ *wire Electric Light* ni apa ile igbọnsẹ Ereko ti wa lẹnu ișẹ rẹ loke, ọkan ninu awọn opo *wire* wọnyi, bẹni ojiji *Electric* yi mu lojiji, bi *wire* kan ti bã lọrun bẹni o mu ẹjẹ rẹ titi ọmọkọnrin na fi re bọ bi eso ti o si di oku bi idan. Ori lo yọ Ọgbẹni Stowe, ẹniti o f'ara gba diẹ pẹlu awọn onișẹ miran lọjọ *Wednesday* ọsẹ to kọja ti agbako yi șẹlẹ. Ki Baba șọ ni.

KẸ PẸ ẸNYIN ỌLỌJA KẸ PẸ.

Ni *Monday* ọsẹ to kọja ni a gbọ wipe awọn onilu da awọn obinrin to npatẹ ọja ilẹkẹ ati awọn nkan miran l'Ẹhin-ogba lọ si Oke Arin lẹba ibusọ ekute ti Munisiba șe: a gbọ wipe a ti kan 'gi mọlẹ nibẹ fun buka ti awọn ọlọja wọnyi yio ma patẹ; ohun ti a fẹ mọ nibẹ ni wipe ọfẹ ni 'busọ ti Ijọba nșe fun awọn ẹni wọnyi, ẹwẹ ẽlo ni nwọn o ma san fun awọn unisiba?

EYI ARA!

Eti wa kun pupọ fun iwa janduku ti a ngbọ wipe ọmọ ọjẹka to nwa mọto nhu nisisiyi nipa fifi ọgbọn ẹtan mu awọn obinrin wọ inu moto lọ si ọna jijin, fun iwa ti ko tọ suna, a fi ọran na le ẹnyin ọmọ-ọba lọwọ.

Ẹ YONBO ON'ȘẸ-NLA.

Awọn ẹgbe Ansar-ud-Deen kekere pa bamba i ni Ita Balogun lalẹ ọjọ *Sunday* ijeje, nigbati nwọn nșe iwasu fun aisun ọdun Tafuseri; bi o ba de ibẹ ẹnikeji yõ ni gbogbo rẹ ri bi oșupa ọjọ mẹdogun, gbogbo awọn ọmọge ati awọn ero iworan to sãfu lọ bi ilẹ bi ẹni, k da bi enia ju abẹrẹ si oke, ko le balẹ; a șeyi șamọdun o.

TOWN COUNCIL.

Ẹ jọwọ ẹ ba ni bojuto titun oju gọta to mbẹ ni Ita Apatira ati Ita Kọsọkọ șe, gẹgẹbi a ti ri, o dabi ẹnipe ipo ti o mbẹ loni ko ba ti ode isisiyi mu.

---

ẸJỌ IWE-IPINGUN TI ỌGBẸNI W. R. HARDING NI GANRAN.

*A yi si ede Yoruba lati inu Nigeria Daily Times,* 21/3/28.

Ọgbẹni W. R. Harding jalaisi ni England ni ọjọ 18 January, 1927.

Awọn ọmọ oku tako Iwe ipingun na wonle, ni Kotu Ganran ti Nigeria, Herbert Agboọla Harding ati awọn mẹrin miran.

Gbe tasi ija nipa ofin si Henry Carr ati John Randle. awọn Baba Isinku.

Awọn to pejọ gẹgẹbi ọmọ William Richmond Harding ologbe fẹ yi Iwe-ipingun ti nwọn gbọ pe baba wọn șe lagbodanu, nitoriti ko lẹsẹ nilẹ.

A pe awọn ti a pe lẹjọ gẹgẹbi Baba Isinkun gẹgẹbi o ti wa ninu Iwe-ipingun na.

Orukọ awọn Lọya to wa fun awọn ti o pẹjọ ni wọnyi: Ọgbẹni Franklin, Kayode, T. A. Doherty, Jibowu ati Baptist.

Orukọ awọn Lọya ti awọn Baba Isikku leyi: awọn Ọgbẹni Ajasa, E. O. Moore, orukọ Lọya ti Fourah Bay College ni A. Alakija.

Tọtun tosi ni nwọn ti fi Iwe ẹjọ ti nwọn fẹ ro șọwọ si Kotu.

Ninu ẹjọ awijare ti awọn Lọya awọn ti a pe lẹjọ ninu nwọn sọ pe awọn to pejọ so to lẹnu sisọ ti diduro ti agere Iwe-ipingun na duro.

Lọya si sọ pe o yẹ ki nwọn tete yanju bi awọn ti o pẹjọ ni ẹtọ lati pe e tabi nwọn ko ni, awọn alawijare (*Defence*) sọ pe lotọ awọn ti nwọn pẹjọ

jẹ ọmọ W. R. Harding faufau, ṣugbọn ohun ti awọn nsọ ni pe gẹgẹbi a ti bi W. R. Harding ni Saro ati pe awọn obi rẹ si jẹ awọn ẹniti nwọn gbarede Oyinbo ni ilu Saro na, nitorina Ọgbẹni W. R. Harding ko le gbeyawo lona ti ọmọ-ibilẹ l'Eko ki o wọ, ọrọ wa dọgba pe ti Kotu ba ri pe awọn apẹjọ ko ni ẹsẹ nilẹ lati pe e, njẹ ẹjọ yio di tituka, ṣugbọn ti ẹsẹ awọn mejeji ba duro bi "I", njẹ Kotu yio ma ba ẹjọ na lọ; Kotu si fi riro ẹjọ na si ogunjọ oṣu March, 1928.

Nigbati a pe ẹjọ na lana, Ọgbẹni A. Alakija ẹniti o wa fun Fourah Bay College sọ pe on ro ti bi awọn apẹjọ ni ẹtọ lati pe ẹjọ tabi nwọn ko ni, si fifi akoko tafala. O ni awọn apẹjọ ko gba iwe Baba-isinku tabi ki nwọn wa ọna miran lati ṣe itọju nkan oku, Ọgbẹni A. Alakija sọ pe nkan ti nwọn nbere lọwọ Kotu ni lati sọ Iwe-ipingun na di Amunimuye, o ni ti Kotu ba ṣe eyi yio jẹ itẹlọrun fun tọtun tosi, yio si din inawo miran ti o le wa nidi ẹjo na ku, o ni ki a mu ọrọ ti Ọgbẹni Moore le ri sọ, ni ti awọn Baba isinku, on ko mọ bi ẹsẹ awọn aṣoju ẹbi Ọgbẹni Harding, ti nwọn le ni ipin ninu dukia oku lo pe si Kotu, ati pe nipa bẹ sẹria tabi idajọ ti Kotu le da nipa ti ọmọ ale ko ṣe ọmọ ale ki yio ta ẹnikẹni lara ninu wọn, Kotu le tun ma ṣe iranmu kiri, ti a ba pa Iwe-ipingun na loku. Ọgbẹni Alakija so pe on ko ni jọjọ l'apa pe ki Kotu sọ Iwe-ipingun na d'ọrịṣa lati tako ẹto awọn ti o pe ẹjọ, o ni on mura lati sọ Iwe-ipingun na di nkan ku.

Adele Adajọ Agba so pe on mo pe idajọ ki idajọ ti on le da lori ẹjọ yi ki yio jẹ ailesọsimọ, ayaṣebi ti idajọ na ba ta awọn ti nwọn jẹ'jọ kulẹ.

Ọgbẹni Moore ni ki awọn apẹjọ sọ bi nwọn ti jẹ si oku.

Lọgan ni Ọgbẹni Kayọde na,wọ to bẹrẹ si mu iṣẹ ọrọ sisọ ṣe.

Gẹgẹbi ọrọ Iwe-ipingun ti a so pe Ologbe W. R. Harding ṣe ti wi, o ni on fun awọn ọmọ on mẹrin, Theophilus Harding, Herbert Harding, Adolphus Harding ati Agnes Ọmọlara Harding ni ogun pọnun (£20), ki nwọn pin ni pọnun marun-marun, o ni ki awọn Baba-isinku on dupẹ lọwọ wọn fun iwa ainifẹ si on."

Ọgbẹni Harding ta Ile-iwe Giga Fourah Bey College ti Saro lọna ẹgbarun pọnun (£10,000).

*A o ma ba bọ.*

---

## AWỌN AKỌWE OYINBO ONIṢOWO.

Lati ọwọ Kekere Awo.

Si Oniwe Irohin *Eko Akete*,

Mo bẹrẹ f'oji,

Awọn ara ilẹ yi, papa awọn enia dudu, eyiti o ba ti le jaja laju diẹ tabi ti o ri oye iwe diẹ ati Akọnta ṣiṣe tabi ti o le jaja mọ iba oyinbo melo kan lati fi ba oyinbo sọrọ, ko si iṣẹ kan ti nwọn nfẹ lati ma ṣe bikọṣe iṣẹ a nta ọja fun awọn oyinbo onisowo.

Ki lo ngbe ẹlomiran debi a nlọ ṣiṣẹ akọwe Ṣọbu fun awọn oyinbo; ẹlomiran nfẹ wipe ki a ri mi pe mo ntaja ninu Ṣọbu, awọn ẹlomiran ti nwọn ba wa iṣẹ titi ti nwọn ko ba ri lo nmu wọn tọ awọn oyinbo lati ṣiṣẹ ọja tita fun wọn.

Ero ti ọpọlọpọ ẹlomiran mba lọ ṣiṣẹ yi awọn nikan lo ye, ṣugbọn awọn ẹlomiran nwọn a ma ṣiṣẹ yi loju wa, bi ẹnipe nwọn ko wa lati fi ṣe ohun anfani kan fun ara wọn tabi fun ẹnikẹni bikoṣe lati fi ṣe gbajumọ tabi iwa janduku, awọn ẹlomiran ẹwẹ si mbẹ, ti nwọn nda aniyan ki awọn le fi iṣẹ yi ṣe rere jalẹ.

Awọn tani nwọn fi iṣẹ yi ṣe iṣe gbajumọ tabi ti nwọn fi nhuwa janduku, eyiti o mu ki awọn oyinbo ba wọn jagbọn-kọgbọn nisisiyi ti o si mu ki nwọn sọ enia rere di enia buburu, eyiti awọn Yoruba fi npowe pe "Ẹru kan lo nmu ni bu igba ẹru" awọn ni ẹniti o jẹ wipe nigbati nwọn ba ṣe wahala titi ki nwọn to ri ohun ti nwọn yio mu lọ dogo lati sọfa (*mortgage*) tan fun awọn oyinbo, yala ẹgbọn kan ara wọn kan tabi baba wọn kan lo ti wọn siwaju bi ogunran lọ si Ẹhingbẹti lati le ma ri okele bu sẹnu ati lati le ma ṣe gẹgẹbi ọmọ-enia, ti nwọn ba si joko lori iṣẹ na tan, ko ni tọjọ ko ni to oṣu, nigbati oyinbo ba fẹ ka ọja bi oṣu kan, oṣu mẹta tabi loṣu mefa, a o gbọ wipe ọja din bi igba, ọdun, irinwo tabi ẹdẹgbẹta lẹṣẹkanna agbare wa agbereṣọ, ohun ti nwọn fi sọfa fun wọn di tita, ni-gbanjo nipa aṣẹ kotu, bi ohun idogo na ko ba si kaju owo ti o din, ọran iyan ni ki nwọn tun mu wọn lamuwa lati ma ko irabi iyoku, eyiyi ni, owo ti o ba tun ku silẹ lati san,

Awọn tani ẹniti ọran yi nbawi julọ tabi ti o gbe ẹru ọran na kari bikoṣe awọn ẹniti o lọ duro fun wọn.

Irufẹ iwa wo lo nm'ọja awọn ọmọ ilẹ yi din, ti ọwọ wọn ba jaja le tẹ kuku ida, nwọn a ma nawo olowo fa bi nwọn ti fẹ, nipa ṣiṣe ohun ti o ju wọn lọ nipa ki ko owo-olowo fun obinrin nipa fifi mu ọti tabi awọn enia janduku miran gbogbo ti o nmu wọn gbe ọna onjẹ wọn sọnu.

Nitorina ti a ba gbọ wipe ọja ẹlomiran ndin, ki iṣe ohun iwuri fun wa lati daro wọn danin-danin, nitori a ti mọ irufẹ iwa janduku ti awọn enia dudu tabi awọn ọmọ-ilẹ yi miran nhu ni Ṣọbu oyinbo wọnyi.

Awọn ẹniti a le ba kẹdun tobẹ lori iṣẹ wọn nigbati a ba gbọ wipe ọja wọn din, ni awọn ẹniti awọn enia ma wa "gbelagbeda" nipa mimu ete iwa janba wa ba wọn eyiyi nipe, ki nwọn ti ma ba wọn ṣe onibara pọ titi ki nwọn ma ṣe dara-

dara pẹlu ara wọn nigbati o ba si ṣe ti nwọn ri wipe owo ti wọ owo ẹsẹ ti wọ ẹsẹ tan ki nwọn si gba ẹru lọwọ wọn ki nwọn si ko wọ igbẹ lọ bam-bam, bi akọwe na ba jẹ ẹniti ki ifi ẹsẹ ẹhin de'le, o di gbese ni iyẹn; ọ·auyan ni pe ki o wa owo na lọnakọna ki aseko ọjọ kika ọja to de bibẹkọ awọn oyinbo yio ti Ṣọbu oluwarẹ titi yio fi ri gbese ọran rẹ san, bi oluwarẹ ba san gbese na, bi o ba tun wu awọn oyinbo na nwọn yio ṣi ilẹkun fun akọwe na papa, bi akọwe na ko ba mura gidigidi bi nwọn ti nti ilẹkun rẹ bẹni nwọn nṣi fun ẹlomiran, bi akọwe na ko ba si ri ekọro kan nipa gbese ti o da oyinbo ko mọ bi ẹnikan lo gbe lagbeda bi ẹnikan kan, tulasi nwọn ni lati gba owo wọn, bi o ti wu ki nwọn fẹran akọwe na to, iru ẹni bẹ ni o yẹ ki a ma ba kẹdun, nigbati a ba gbọ wipe nwọn lu gbese nwọn si da wọn duro lẹnu iṣẹ wọn.

Awa ti a nsọrọ yi, a mọ irufẹ wahala ati ewu ti o mbẹ ninu iṣẹ a ntaja fun awọn oyinbo ni aseko yi gbogbo nkan lo ti yipada, ko jọ igba kan ti o jẹ wipe awọn oyinbo fun ara wọn ni nwon o ma wa ẹniti nwọn yio fi sinu Ṣọbu wọn, ki iṣe aseko igba na li a wa loni, agbaia kaka ni nwọn fi ngba wọn si Ṣọbu nis siyi pẹlu ohun iduro ks duro ti oluwarẹ le mu bọ ni.

Njẹ ti o ba jẹ wipe ẹnu awọn akọwe wọnyi ko si iṣẹ wọn daradara, ki nwọn si ma ṣe apejọ larin ara wọn gẹgẹbi awọn oyinbo wọn ti nṣe apejọ ti ara wọn ṣe iba dara pupọ, munafiki ati mọnani ki a ma jin ara ẹni lẹsẹ ẹhin ko ni le jẹ ki awọn le ṣe bẹ; on na lo si ntọ wọn loju la loni, ti ko fi jẹki nwọn jọ awọn oyinbo wọnyi loju mọ, iwe ti nwọn ko fi le ri ọwọ yogbe lori iṣẹ, ti nwọn nṣe fun wọn papa nipa opolọpo wahala ti nwọn nṣe titara-titara ki nwọn to le ri ọja ti yio jọ oyinbo loju ta,

A sọ lọsẹ to kọja wipe awọn akọwe wọnyi ni Ṣọbu wọn omiran yio ta ọja to ẹgbẹrin pọnun ki nwọn to bẹrẹ si fun wọn ni owo ere-iṣẹ bi pọnun kan tabi ṣile mẹdọgbọn lori ọgọrun pọnun, ti o ba jẹ wipe ẹnu wọn ko daradara irufẹ wahala ti oju awọn nri nisisiyi ko le to bẹ arara.

Ẹ jẹki nfun nyin ni aperẹ kan lati le fihan nyin bi o ba jẹ wipe abusọ ni a fi eyi sọ.

Ẹlomiran ninu awọn akọwe wọnyi fi nkan bi ẹdẹgbẹta tabi ẹgbẹrun pọnun duro ki nwọn to le ri iṣẹ yi ṣe, ẹniti o gbe ile rẹ ti o fi duro ṣọwọ oyinbo lai si ani-ani, ẹmi rẹ kekere lo jẹ lori ohun ini tamtam na, nwọn a ma san pọnun mẹta tabi mẹrin owo oṣu fun wọn, bi nwọn ko ba ta to iye ti nwọn nfẹ nwọn ko le ri owo ere-iṣẹ gba, aiyafi owo oṣu nikan.

Loju ti wa iṣẹ wọn pọ lọpọlọpọ ju iye ti nwọn nsan fun wọn lọ, ko to fun awọn akọwe arara lati gbọ bukata wọn, pataki nigbati nwọn ko gbọdọ ta ọja awin si ode.

Ṣugbọn tani a ba ri bawi bikoṣe awọn enia dudu papa ti nwọn ngba irufẹ adehun baun; awon tikarawọn ko ṣai mọ wipe pọnun mẹta losu ko le to fun wón lati gbọ bukata, pẹlupẹlu nigbati nwọn ti fi nkan ẹdẹgbẹta tabi ẹgbẹrun duro nwọn ko ṣai mọ wipe gbese ni irufẹ iṣẹ bẹ, kini ha ṣe ti nwọn ko fi panupọ lati kọ owo-oṣu ti o kere ba yi.

Nipa bẹ eyi fihan wipe awọn enia dudu ko le panupọ nipasẹ ọrọ iṣẹ tabi awọn nkan miran ti o le jẹ ohun irọrun fun wọn.

Bi ẹnikan ba kọ iṣẹ kan silẹ nisisiyi pe on ko ṣe mọ nitori sababi ọna ti a la silẹ yi, a o ri ẹgbaji enia ti yio sure lọ si ibẹ lati ṣe iṣẹ na, nwọn a si ma pa owe bayi pe:—"Wan an tọrọ san ju wan an gbe'le lọ" nwọn a si ma ge ara wọn lẹhin titi oyinbo yio fi mu eyikeyi lọ wọn,

Ko si oyinbo ti nwọn ma fi sinu Ṣọbu, ti ki yio ni akọwe ti yio ma ranlọwọ ati boyi Ṣọbu pẹlu, iṣẹ tirẹ ko ju wipe ki o gba owo ọja ti nwọn ba ta, akọwe lo ni lati ma ko'rabi wahala ti o ba ku lati ṣe, bi aseko lati ka ọja ba nto bọ ni nwọn o ma kọ iwe kẹrẹkẹrẹ kan loju wọn o ti ṣ ṣẹ julọ, ti a ba wa lọ wa bọ ko da ni lojù pe a le ri eyiti nwọn yio gba nkan iduro lọwọ rẹ ninu wọn ki nwọn to ka ọja le lọwọ, bi a ba ni ki nwọn ma ṣiro iye inawo ti nwọn yio ma ṣe lori awọn oyinbo miran ti nwọn nfi sinu Ṣọbu wọn ẹru yio pa ọkọ, nwọn ko si bikita fun u arara nitori ọmọ iya kanna ni nwọn jẹ.

Gẹgẹbi a ti nkọ awọn enia dudu ni oye ohun ti yio ṣe wọn lanfani ẹwẹ ti a si ntọri wọn si ọkankan ọna bi ọkọ ni nwọn ngba si wa lẹnu lai si iyapa ẹnu tabi lai si iwa aibikita nibẹ, iba dara julọ, iwa arankan kole jẹki nwọn le ri anfani ara wọn jẹ.

Bi ẹnikan ba dide nisisiyi ti o fi ake kọri pe ẹ jẹ ki awọn so panpa lori ẹgbin ti awọn nri ni idi iṣẹ, a o ri ẹniti yio tun pada yọ kẹlẹkẹlẹ lọ ṣe ilẹdi rẹ lọdọ rẹ lọdọ oyinbo ti oluwarẹ nṣe iṣẹ fun pe lamurin fẹ fi iṣẹ silẹ lapandoco o ti ri ẹru nyin ko jẹ daradara, bi oyinbo ba si gbọ bẹ kẹ aiya wọn yio ja, nwọn a sure lọ ka ọja, alalikuwa ajo ki o ba le dara fun gbogbo wọn ma ni oluwarẹ fẹ ṣe bi oyinbo ba si ka ọja ti nwọn ri wipe ko din, rikiṣi oluwarẹ ti nwọn ti ṣe ki yio fi oyinbo laiya balẹ lati jẹki oluwarẹ ma ba iṣẹ rẹ lọ; ẹniti nwọn si ṣe bayi fun, yio ma ro ninu ararẹ pe kini oyinbo awọn ri ki o to wa ṣe bayi pẹlu on, lẹhin igbati o jẹ wipe aseko ọja kika ko i ti to, ẹwẹ ti nwọn ko si fun on ni iwe tẹlẹ pe awọn mbọ wa ka ọja tabi awọn mbọ wa da on duro lẹnu iṣẹ.

Bi oyinbo ba si ṣeṣi da oluwarẹ duro patapata, ara wọn na ni yio tun gbe abẹlẹ wa ẹlomiran dipo fun u ti nwọn ti da oluwarẹ duro eyiyi ni ohun pataki ti o nba awọn ara ilẹ yi ja pupọ ti ko jẹ

ọpọlọpọ wọn le ni lari tobẹ ti orungbẹ iṣẹ ti yio na wọn lẹhin fi ngbẹ wọn.

Awọn re kẹ, bi nwọn ba ti le jaja jade kuro ni Ile-iwe, iba igẹsi ti nwọn ba mọ nwọn ko ni fẹ fi ko iṣẹ *Carpenter*, *Bricklayer*, *Goldsmith* tabi ti *Tailor*, bikoṣe iṣẹ akọwe ni ọfisi tabi ni Ṣọbu, ọna ti nwọn le ri anfani iṣẹ oyinbo jẹ awọn fun ara wọn ni nwọn nfi ọwọ ara wọn gbe sọnu, o si ntọ wọn loju la loni o ba wi fun titi nwọn ki yio gba aba ati imọran wọn, bikoṣe ifẹ inu ara wọn, eyiti koẹe kuku ti o mọyan lori fun wọn.

Ebi npa ọpọlọpọ ọmọ ilẹ yi loni tobẹ ti omiran fẹrẹ le gbe igba bara tani nṣe wọn, tabi ki loṣe ti nwọn ko fi le tete ri iṣẹ ṣe? awọn fun ara wọn lo nṣe ara wọn, ohun ti apa wọn ko ka ni nwọn ma nfa lẹ lo si nyọ silẹ fun wọn to, eyiyi lo ṣe idena riri iṣẹ wọn laseko yi ti ebi iṣẹ npa wọn.

Nipa aifẹnu-ṣọkan ti iṣẹ ti nwọn nṣe fun awọn oyinbo ti a nsọ lẹsan li a tun wa pada si yi nitori a ko i ti fori bi o ti tọ awọn enia dudu le ṣe ti; ara wahala ti nwọn nṣe lo nta wa li a fi ngba ọran wọn dun to bayi, ṣugbọn o jẹ ohun ẹdun ọkan fun wa lati wipe irufẹ itara bayi nkan lasan lo jẹ fun wọn, ki Ọlọrun maṣe fi ebi inu pa iran enia dudu. *Amin.* Owo asingba tabi Saka-odọdun *(Income Tax)* ti Ijọba nja fun bi o wu Sati O le gbe fo lori wọn.

Ohun ti a fẹ ni wipe ki awọn akọwe wọnyi ṣe ni wipe ki nwọn ṣe ipanupọ ti ki iṣe ti munafiki tabi mọnani ani ipanupọ ododo, pe ponun mẹta tabi mẹrin ti nwọn san fun wọn loṣu ko le wọ arara, lẹhin igbati o jẹ wipe bi awọn ba ti nta ọja si lẹhin ẹgbẹrun pọnun li nwọn o ma fi san komi-ṣanni fun wọn, lai jẹ wipe nwọn ta nwọn ko ta kọmiṣanni wọn yio ma lọ dede gẹgẹbi owo oṣu.

Ti gbogbo awọn akọwe ba fi mọṣọkan bayi, o da wa loju wipe awọn oyinbo oniṣowo ko le binu lọ mu awọn oyinbo funfun ẹgbẹ wọn wa sinu Ṣọbu ti o mbẹ kakiri larin ilu nitori nwọn ti mọ irufẹ wahala ti oju wọn yio ri ẹwẹ nwọn a si mọ irufẹ inawo rẹpẹtẹ ti yio ma jade ninu apo wọn, nipa bayi ko ni le jẹ ki nwọn le sọ wipe awọn yio ma fi oyinbo funfun ẹgbẹ wọn sinu Ṣọbu igboro kakiri.

A tilẹ ti gbọ ni sa kan ri pe awọn enia dudu ti nṣe ẹgbẹ akọwe Ṣọbu oyinbo oniṣowo ri, ṣugbọn a ko ro wipe iru ẹgbẹ bẹ ṣi mbẹ nisisiyi, bi ẹgbẹ na ba ṣi nbẹ, o yẹ ki nwọn ṣe iwe si awọn ẹgbẹ awọn oyinbo oniṣowo lati fihan gedegbe pe pọnun mẹta tabi mẹrin ti nwọn nfun wọn ko le wọ fun wọn arara, fun akọwe ti o nta ọja Ṣọbu larin igboro, bi eyi ti a wi yi ko ba si jẹ nkan loju nyin, iyoku ku si ọwọ nyin, anu wahala ti ẹ nṣe lori iṣẹ eyi lo nṣe wa.

## Ẹ KU ỌDUN, Ẹ KU IYEDUN!

Ni ana Jimọ ti nṣe ọjọ 23 oṣu yi, awọn Musulumi wa nile-loko loke-lodo kakiri ilẹ Nigeria lo kirun Yidi "Eidil Fitri" eyiti nwọn npe ni irun ọdun kekere, o si jẹ ọdun 1347 ọjọ ontsa sun Anabi Mọmọdu eyiyi ni ẹgbẹrun ọdun, o le ọdun, ọdun na le mẹta-din-ladọta ti nwọn ti bẹ rẹ si ka, tabi Hijirat, eyiyi ni awọn Musulumi npe ni Sa-Anabi won ni ilu *Mecca* ki o to sa asala lọ si ilu *Medinat* ni ibi ti nwọn fi ori iya rẹ sọlẹ si.

Gẹgẹ bi a ti wi ninu wosika ti ọsẹ to koja, Alufa Lemọmu Mọmọdu Ligali olohun iyọ yio gbera ni ile ni dede agogo mẹsan, ki agogo mẹwa to de ori rẹ, ẹsẹ awọn Janma ti pe perepere ko ku ẹsẹ kan lẹhin.

Bi agogo mẹwa ti koja diẹ ni Lemọmu paṣẹ pe ki nwọn gbe "*Ikamat*" ki nwọn gbe Irun duro, lẹhin ti nwọn si salamọ tan, Lemọmu gbe "*Khutubah*" Iwe-adura nwọn ke si ni ẹhin-odi, nwọn si ṣe adura lọpọlọpọ, patiki ninu awọn adura ti nwọn ṣe ni wipe ki ilu le toro, ki otitọ bori eke ki Ọlọrun di 'gaga gbogbo ohun musiba ohun buburu ti o mbẹ ni ilu, ki o si gbe ilu lekẹ Aluba ti o ba mbẹ ni ilu, olubori rẹ ni pe ki Ọlọrun ṣe ẹdẹ si ọwọn iṣẹ gogo ati ọda owo ti o mbẹ ni ilu ati kakiri ibi gbogbo, ki o si lọra ẹmi olukuluku.—Amin.

A kole rohin ohun ribiribi ti awọn ẹgbẹ Killa Sule ni Ereko, Bawa-allah ni Oluwọle, Savage ni Idunṣagbe ati awọn jakanjakan amuludun ṣe nitori ko si aye nipa eyi lati rohin.

A tilẹ dupẹ lọwọ Sati Ẹniti ko fun awọn miran laye lati gbe ọpa wahala a o kirun, a kirun lọjọ Jimọ dani, nigbati Ọlọrun ti doju wọn lọdun Ileya ti o koja lọ, ti awa na si ti ẹtẹ lu wọn, olukuluku wọn ti lọ mọ ẹwa ni ajẹsun, ẹniti o nleri bebe wipe kaka ki eku ma sese on yio fi ṣe awadanu, oluwarẹ kufi lo kole ṣe kini kan—ọrọ Ọlọrun ki iṣe ohun ti a ọtẹ ṣe, ẹniti o nṣe wahala lati pana ohun ti Ọlọrun mọlẹ o daju wipe Asaba Ọlọrun li oluwarẹ lai si tabi-tabi.

Bi o ti wu ki o ri o yẹ ki a ki ẹnyin Musulumi wa pe ẹ ku ọdun, ki a si ṣe adura fun nyin pẹlu

A ki Mogaji Mumuni Animaṣhawun Alli Ọlọko Sọnni Shitta—(Seriki Musulumi) Abibu Oki Balogun, Bakare Misiun, Alaji Sọnni Giwa, Alaji Mustafa, Alaji Abdu Ramọnu Davies, Sọnni Adewale, Sule Balogun Tairu Animashawun, Bello Alufa (Ita Akọni) Buahari Animashawun, Buari Olokodana, Adamu Animashawun, Kasumu Gbajabiamila Bashọrun, Seidu Tella, Abudu Ramọnu Aranmọletiẹshọ, Alaji Lawani Martin Alaji Tijani Alaji Atobajẹun, Brimah Ọbaninbaṣe Brimah Ẹkun, Alimi Idoluwo, Badiru Abina, A Ọtun, Abudu Rahimi Olowọpọpo, Kekerẹ

Sadiku Sarumi, Brimah Igbo, Sanusi Birikila Kadiri Ijaọla, Abudu Karimi Kọtun, Yesufu Ijaoba, Brimah kekere-ogun, Saka Tinubu, Sule Shitta, Alufa Belo Arọwasi, Ayilara Giwa, Disu Matti, Muritala Alaji, Abibi Nọla, Sule Abọmafọ: A ki Chief Lemọmu Mọmọdu Ligali ati awọn Ratibi rẹ, a ki Jamat Alukurani ati awọn jakanjakan gbogbo ni ilu ati ni ẹhin-odi, ẹ ku odun, ẹ ku iyedun, a ṣe'yi ṣamọdun—Amin,

A nfẹ ki ilu yi roju, a nfẹ ki o toro, a nfẹ ki Ọlọrun pana ofin-kofin ti o le jẹ inira fun ilẹ yi; oyinbo ni o, enia dudu, Kiriyo tabi Imale ni, ẹnikẹni eyi o wu ti o ba ni ilẹ yi ko ni roju ko ni toro loju on, Ọlọrun Ọbangiji lo ma dajọ fun —ẹ ṣe Fatiha ẹ ko gbọdọ fi ọwọ rẹ bọju.

Bi ilẹ yi ba roju ti o ba toro yio rọ tẹru-tọmọ ni, ko ni si kini un o jẹ sun ni yio p'ọlẹ. Ẹ yonbo onisẹ-nla, *sala allahu-Alaihi-wasalim*.

Emi ni tiyin nitotọ,

KEKERE AWO.

---

## ORI III.

# IWA—ẸGBẸ KIKO ATI APẸRẸ.

(*Translated from "Character by Dr. Smiles"*).

APA KINI.

---

Titi lọ ni ẹkọ Inu-ile-ni gasikia ki ipin. Ṣugbọn nigbati o ba ṣe, odun ngori odun, ọna miran a tun ṣi silẹ eyiti a ngba kọ ẹkọ iwa; a bẹrẹ si kọ ẹkọ ni ile-iwe, a di ẹniti o ni ẹgbẹ ati ọrẹ awọn eyiti itubọ kọ ni, ni iwa nipa awọn àṣá tabi apẹrẹ ti a nri.

Gbogbo enia, ati omọde ati agbalagba—pāpa awọn ọmọde-ko le ṣai fi ara we awọn enia ti nwọn nba rin.

Ọrọ ẹkọ ti iya George Herbert fun awọn ọmọ rẹ okunrin ni eyi, "gẹgẹ bi onjẹ ti a njẹ si inu ba ti ni lāri to ni ara lile wa fi ito, bẹna ni nipa àṣá tabi ajumọ ṣọrọ-pọ pẹlu awọn ọrẹ tabi ẹgbẹ rere tabi buburu a mu ni di enia rere tabi enia buburu."

Ni gasikia, ko si ọgbọn rẹ ti awọn ẹniti a nba rin pọ ko fi ni ni agbara lori iwa wa Alafarawe ni gbogbo enia jẹ, iṣe-ẹnu sọrọ, àṣá, iṣesi, ilọsi titi de ọna ti awọn ẹlẹgbẹ wọn ngba ro nkan ki iṣai mu wọn lọkan. Burke ni, "Asan ha ni àṣá tabi apẹrẹ jẹ? O jẹ mẹwa. Apẹrẹ ni iṣe ile-ẹkọ gbogbo ẹda, ko si ibi miran mọ ti nwọn yio kọ ẹkọ." Ọro awiye ṣoki ti o dara pupọ eyiti Burke kọ si ara okuta ni iranti Marquis Rockingham, wọ to gbajẹ nihin: ọrọ na ni eyi:—"Ṣe iranti—jọ—fi ori ti i."

Afarawe jẹ ohun ti a ki iro tẹlẹ, tobẹ ti a ki imọ titi yio fi di ara; ṣibẹ eyi ko din agbara rẹ ku.

Ṣugbọn nigbati ẹniti imu ni gba tirẹ ba ko ẹniti ima gba, nigbana ni a ma nṣe akiyesi iyipada ti ọkan ṣe lara iwa ekeji.

Awọn ti o tilẹ jẹ gbewe-ṣire enia a ma ni agbara lori awọn ti o wa ni sakani wọn.

Idunra, ero ati ilọsi a ṣe kongẹ nigbagbogbo, apẹrẹ ki isi ye ṣe iṣẹ rẹ.

Emerson ni o sọ pe, ani, awọn tọkọ taya ti o t darugbo, tabi awọn ti o ti njumọ gbe pọ fun ọdun pupọ, ni aiye, kẹrẹ-kẹrẹ nwọn a jọ ara wọn; bi nwọn ba si le pẹ pupọ ni aiye, a fẹrẹ le ma mọ wọn ni iyatọ.

Bi eyi ba jẹ otitọ niti agbalagba, a ko le ṣẹṣẹ sọ ti awọn ọdọ mọ, awọn ti o ṣi wa ni gbẹdẹgbẹdẹ ti o si ya lara lati kọ iwa ati iṣe-ẹnu-ṣọrọ-ṣi, awọn ti o wa yi wọn ka.

Sir Chaales Bell ninu ọkan ninu awọn iwe ti o kọ sọ pe, "Ọrọ ti pọ nipa ti ẹkọ, ṣugbọn loju mi o dabi ẹnipe a gbe oju fo ti apẹrẹ, eyiti o jẹ labori. Pataki ẹkọ mi, ni apẹrẹ eyiti awọn ẹgbọn mi fi lelẹ fun mi. Olukuluku wa kọ lati duro fun ara rẹ, ki a ma gbe oju le ẹnikan, nipa ṣiṣe afarawe emi na papa si kọ eyi."

Awọn ọna wọnni ti imu ni ni iwa ti o wa di ara fun ni, nigba ewe ni iwọnyi ni agbara ju lori ẹni. Bi a ti ndagba si, apẹrẹ ati afarawe a di àṣá, kẹrẹ-kẹrẹ eyi a papọ di iwa, eyiti o nipa tobẹ gẹ, ki a to ṣẹju pẹ, lairo tẹlẹ, a ti di oluwa ẹni.

A gbọ pe, ni ọjọ kan, Plato nba ọmọde-kunrin kan wi, pe, o nṣe ire- kọlọkọlọ. Ọmọde-kunrin na ni, "O nba mi wi fun ohun ti ko to nkan."

Plato dahun o ni, "Ṣugbọn àṣá ki iṣe ohun ti ko to nkan."

Bi àṣá buburu ba di iwa tan a jẹ gaba a di ọni-amuni-mada tobẹ gẹ ti, nigbamiran, enia le korira àṣá wọnyi, ṣugbọn ki o ma le ja wọn silẹ. Nwọn ti di ẹrusin awọn iwa ti nwọn ko ni agbara lati kọ silẹ.

Nitorina ni Locke ṣe sọ pe ki enia ni ọkan ti o fi le tẹ iwa, jẹ ki ọkan ninu awọn eyiti o jẹ pataki ninu ọna ẹkọ iwa rere.

Lotitọ ni ọpọlọpọ ninu ẹkọ, iwa huhu nipa apẹrẹ jẹ eyiti iyọ jade pukẹ, ti a ki isi ro tẹlẹ, ṣugbọn, ki iṣe ọranyan fun awọn ọdọ ki nwọn wa gbunduku ki nwọn ma ṣe afarawe awọn ti o wa yi wọn ka. Ihuwasi awọn tikara wọn—ju ti awọn ẹgbẹ wọn lọ—ni ila ọna ti nwọn yio tọ ni aiye. Olukuluku wọn ni o ni ọkan ara rẹ ni o si le ṣe ifẹ inu ara rẹ, eyiti ti o ba duro ti pẹlu igboya yi mu le yan irufẹ awọn ọrẹ ati ẹgbẹ ti ọkan rẹ nfẹ lati ba rin pọ. Nibi aini ọkan ara ẹni ni awọn ọdọmọde, ati awọn agbalagba pẹlu, fi idi ẹrusin tabi ti nwọn fi iko-bẹrẹ, ti nwọn a di alafarawe awọn ẹlomiarn.

*Translated by*

ADEYINKA AJAGBE-ỌSA

EKO AKETE

EKO, SATURDAY, MARCH 24, 1928

## "ILABIRU" TO BA Q NI'LẸ YI TI R'ẸṢIN

Kò dẽde ti a fi kọ irufẹ ọrọ bayi s'oke iwe pataki wa ti ọsẹ yi, nitori nigbati a wo iwaju wo ẹhin ni igboro ilẹ yi, ohun ti pupọ ninu wa ma nsaba lati gba'ra jọ ṣe ju ni ohun ti yio rẹ ọmọ ẹnikeji wa si'lẹ: ki a fun nyin ni apẹrẹ kan, bi awọn "Akẹran" ba ṣeṣi mu oloruko kan ni ilu eyiti a nwi yi ti pẹ, irohin mimu na yio ti tan ka origun mẹrẹrin Eko, ki o to to oṣalẹ, nwọn ti gbọ jakejado *Nigeria* pe nwọn ra Lagbaja mu; nigbana ni iwọ yio ma gbọ ọkan ko j'ọkan ọrọ iṣọnu bayi, "ọwọ tẹ ara'le rẹ wayi, ng o wi fun ẹ?" "Ṣiọ! galegale rẹ pọju" "ko ṣe bi o ti mọ," "obinrin to nkowo fun ko ni'ye." "Afojudi rẹ nkọ? O to ti ẽgun kekere to nki baba rẹ ni ọ̃ku" ati irufẹ maṣaṣi ọrọ bawọnni; bayi ni awọn enia wọn ma nj'oye "ikoko dudu ti ko gbọ ti ara rẹ to ngbọ t'ẹni-ẹlẹni;" ṣugbọn ta la ma yẹwo ti a ko ni ba nkan laifi ni sakani rẹ? Aro ẹnit'o ṣa yọ la urẹ; bẹna ni, olukuluku lo nj'oye orule b'aja mọ'lẹ, aṣọ bo'ṣe idi. Ipa ni a le fi ri idamẹta enia ki nwọn tilẹ daro irufẹ ẹni bẹ. Iwa yi tubọ npeleke larin wa nibi tobẹ ti ominu fi nkọ ni pe sibẹsibẹ o da bi ẹnipe pupọ kc ti mọ ohun ti awọn nṣe: ẹtẹ awo ni ẹtẹ ọgbẹri, owe Yoruba ni; ko si ohun meji ti a nfẹ loju mejeji nisisiyi ju Iwa Ifẹ ati Iso'wọpọ fun iṣẹ rere gbogbo ti yio ma mu ilu ati Iran wa tubọ ma tẹ atẹsiwaju lọ.

Ẹnyin ẹ tilẹ wo bi ògì ti parada to d'ẹkọ to, ninu iyipada tamutamu ti o farahan gedegbe lara awọn Oyinbo ti a npe ni "Kọ̃rã" (*Syrians*) ti nwọn ti igbo meje ati ọdan meje wa si ilẹ yi l'eni tere eji tere, ti nwọn si fi Ebute Ẹhingbẹti ṣe ile nibiti nwọn ngbe nta ilẹkẹ iyun wọn nigbana: awa papa gbọnju mọ pupọ ti nwọn ko ni isọ ambọsibọsi ṣabu tabi ile ti nwọn le ko iyun wọn wọnyi si nigbana, bikoṣe pe ki nwọn na wọn s'ori apoti pagunpagun bi meji mẹta ti a to po fun awọn ero onibara wọn.

Nigba pupọ ẹwẹ, nwọn a ma kiri ọja yi kakiri igboro ilu nibi, nwọn a sọ awọn iyun na s'ejika pẹlu irahun ti o dabi ti ẹniti ebi ti fẹrẹ yọ loju, ẹ sa gbọ ohun irahun wọn igbani na; kọ̃-ọ-ọ-ọ rá-à-à-à! kọ̃-ọ-ọ-ọ rá-à-à-à!! kọ̃-ọ-ọ-ọ rá-à-à-à!!! bayi ni aṣa awọn ajeji yi ni igboro ilẹ yi niwọn ọgbọn ọdun sẹhin.

Ṣugbọn loni nkọ? Awọn Oyinbo kanna yi ti kuro ni ẹniti o nfi ara gba otutu ti ile wọn lailai-ani Ẹhingbẹti, ki nwọn to le ribi ta panduku wọn, nwọn si ti di ẹniti o nra ile kun ile, ti nwọn nkọ asẹ kun asẹ, ti nwọn si nra oko kun oko. Ẹ lọ si Ereko, ẹ o ri ọwọ wọn nibẹ, ẹ lọ si Ita Agarawu, ẹ o ri ọwọ wọn nibẹ, ẹ lọ si Ẹhin Ọgba ẹ o ri ọwọ wọn nibẹ. A ko tilẹ ha gbọ ni sã kan pe ninu wọn jẹ kunmoyo tan, o si npete lati ra gbogbo Ereko "pa" bi a ba fun on l'aye rẹ? Tabi otitọ ha ni ọkan tabi meji ninu wọn bẹrẹ si nhan awọn Alapata wa lenmọ nipa pe ki nwọn fi owo lu awọn malu ti awọn ara wa nṣẹṣẹ ngiri ra ni Sango pa patapata nipa rira wọn ti *Wagon* ti *Wagon?* A tilẹ gbọ pe diẹ ninu wọn tilẹ bọ si owo ekurọ rira nisisiyi; bi ere-ẹṣin-sisa ba si de, iru ni wọn, nwọn ko ni wọn nibẹ

A ko sọ gbogbo eyi lati ṣe ilara wọn, tabi lati fi yọ ṣuti si wọn, ṣugbọn a sọ fun itagiri awọn ara wa nibi ati nibomiran pe awọn ti awọn ẹlomiran ti le ma pe ni "Ilabiru" ninu awọn ajeji to wa si'lẹ yi ndi Araba, ti apa ọmọde ko ka mọ l'ode oni.

Ohun ti a ri pupọ ninu wa si, ko ju ṣiṣe fãri ete lọ, "yanmuyanmu nṣe fuja lai lapa:" ṣiọ! bẹni a bi ni l'Eko ko d'owo.

Ti a ko ba ti bẹrẹ si ronu ohun ti a ti nsọ bọ yi, njẹ asiko to lati jigiri niyẹn fun iso'wọpọ ṣe iṣẹ owo tabi ohun rere miran gbogbo; ki a ye joko s'ẹnu nmi, ki a tilẹ

..un bi ara wa lere, o di "Kọra" melo la ..i ti o ndi *Application* (Iwe Iwaṣẹ) mọ ..iya kiri wa iṣẹ lọdọ Ọba tabi ti Oyinbo ..niṣowo? Awa papa koi ti ri ọkan ki o ṣe ..ọ ri, kaka bẹ, nwọn a s'ọwọpọ larin ara ..won lati da ina owo ti awọn papa silẹ.

Ẹnyin ọmọ iya wa, ẹ ko na ri idi Abajọ ..won bi? Awọn Oyinbo lo ma npa l'owe ..pe:—*what man has done, man can do.* ..eyini ni pe ohun ti ẹnikan ba ti ṣe ..i, ẹlomirad si tun le ṣe bakanna ti ko ..pada. (Ajulọ ko pin s'ọdọ ẹnikan).

Nitorina ẹnyin ara wa, ẹ maṣai da ..gbolohun ọrọ diẹ ti a sọ yi ro, ko yẹ ki ..a ma fi gbogbo ojọ wa "jagun bi ẹru" ..Owe ti ẹnyin agbalagba o!!!

Lãkaye lo ju
K'a ṣiṣẹ bi ẹru ko da nkan.

---

## Ẹ ṢASALATU F'ONIṢẸ NLA.

*Salalahu Alaihi Wasalam!*

[WOSIKA LATI ỌWỌ ATARI AJANAKU]

Mo bẹrẹ f'oji,

Nigbakugba ati ni oniruru ọna ni Musulumi, nṣe asalatu fun Onișẹ-nla; l'aisi ani-ani, Anọbi Muhamọdu ṣe iṣẹ nla ni aiye, iṣẹ rẹ to, o si pọju eyiti enia le ṣe asalatu fun lọ. Ki Musulumi to gbadura, nwọn ni lati kọkọ ṣe asalatu fun Onișẹ nla, ti nwọn ba si gbadura tan, nwọn ni lati tun ṣe asalatu miran pẹlu, bi Musulumi ba ti ri aye to, bi ọrọ ẹsin ba si ti gbona l'ọkan rẹ to, bẹni o fi nṣe asalatu yi fun Onișẹ-nla, ko si si ofin kan pataki ti o wipe a ko gbọdọ ṣe asalatu ju iye igba kan lọ. Ẹniti o ri aye daradara, ti o si le sẹ ara rẹ le ṣe e ni igba ẹgbẹrun ki ilẹ to ṣu, laulafia ni, ko ni laifi.

Oniruru ẹsin ni o wa l'aiye, olukuluku wọn lo si ni onigbagbọ tirẹ tabi ẹniti o nsin wọn. Ẹsin Ọlọrun ti wa ni aiye ṣiwaju ọjọ ibi Anọbi Isa, ki a ma ṣẹṣẹ sọ ti Anọbi Muhamọdu, ṣugbọn ọna ti olukuluku ẹlẹsin fi nsin Ọlọrun ṣiwaju lo yatọ si ara wọn, ti ẹlomiran tọ suna, ti ẹlomiran ko tọ ọ.

Orukọ pupọ ni a le da ni orukọ awọn ẹni nla-nla, ti o ti da oniruru ẹsin silẹ, ẹsin ti ọpọlọpọ ẹda si gbagbọ titi di oni-oloni. Ti a ba ndarukọ awọn ẹni bi Gautama Buddha, Conficius ati awọn jakan-jakan miran pẹlu, awọn Omiran (*Giants*) ninu ẹsin ọpọlọpọ enia ni gbẹgbẹlẹ iwọ-ọrun Afrika ti o wa nibi le ṣai mọ wọn, orukọ ẹsin wọn, ati ọna ti nwọn ngba sin si le jẹ ohun ajeji l'eti wọn, ṣugbọn ti a ba darukọ Anọbi Isa ati Anọbi Muhamọdu, yio tete ye ọpọlọpọ enia, gẹgẹ bi orukọ Ọramfẹ, Ọbatala, Ṣango ati orukọ Irunmọlẹ miran ti dun yungbayungba leti awọn Keferi.

Ẹni nla ni Anọbi Isa, apẹrẹ iwa ifi-ara-ẹni rubọ ni o fi silẹ l'aiye: titi aiye yio si fi parẹ, orukọ Anọbi Isa ko le parẹ l'aiye, ki yio si parẹ ni ọjọ Igbende Alikiomọ; ṣugbọn ọrọ diẹ nipasẹ Anọbi Muhamọdu ati Musulumi ni a fẹ sọ loni.

O di ẹdegbeje ọdun o le marundi-lọgọta loni ti Amina bi ọmọ kan fun Abudulai (Abdallah) ni ilu Mẹka, orukọ ọmọ na a si ma jẹ Muhamọdu. A fẹrẹ le pe e ni Babarinsa ọmọ, nitoripe oṣu diẹ lẹhin ti a bi i tan ni Abudulai baba rẹ fo ṣanlẹ, ti o ku, ko si pẹ pupọ lẹhinna ni Amina iya rẹ tun fi ilẹ bora. Ape to pe, ọmọluwabi, ẹlẹyinju ẹgẹ ni Amina, arẹwa obinrin ni nṣe, o gun, o si ṣingbọnlẹ; bi ṣẹda ni irun ori rẹ ri, ko si si ohunkohun ti o fi le wipe obinrin l'ẹwa, ti Ọlọrun fi du u. Amina ni ẹwa, o si ni iwa pẹlu.

Lati kekere ni Muhamọdu ko ti ni baba pẹlu iya, ṣugbọn gẹgẹ bi Malu ti ko ni iru, Ọlọrun pese ẹniti o nle eṣinṣin fun u; ogbọn ati lakaye rẹ tayọ ti awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni ilu Mẹka, o si korira itanjẹ, irọ aiyederu ati iwa buburu miran gbogbo tobẹ gẹ, ti awọn ẹgbẹ rẹ fi npe e ni "Al Amin" tabi ofofo lati kekere.

Ẹsln ti o gbilẹ ju ni Arabia lakoko yi ni Ibọriṣa, larin iborișa yi ni a si bi Anọbi Muhamọdu si, ṣugbọn sibẹsibẹ, Ọlọrun ti kadara rẹ pe yio ṣe gudugudu meje l'aiye.

O nba iṣẹ rẹ lọ, o nṣowo pẹlu awọn ara Mẹka ati Mẹdina ati jakejado gbogbo ilu Arabia, ko si ibiti okiki rẹ ko kan de; l'aifa a gun lọ titi, nigbati o di ẹni ogoji ọdun gbako, ni o ri iran, ti Maleka Jubrilla yọ si i, ti o si wi fun u pe, Ọlọrun ti yan a ni Woli rẹ lati gbe ogun si Ibọriṣa, ati lati jẹ ki gbogbo enia ti o ti mọ ri tubọ mọ, ati awọn ti ko mọ tẹlẹ ri mọ wipe ko si Ọlọrun miran lẹhin Ọlorun Mimọ nikanṣoṣo.

Bayi, ati lẹhin eyi, ni Anọbi Muhamọdu bẹrẹ iṣẹ rẹ larin ọrẹ, ẹbi ati iyekan, ki o to di igbati o bẹrẹ si tan imọlẹ ẹsin Olorun ni gbangba kakiri ilu Mẹka ati agbegbe rẹ. O di ẹniti gbogbo ilu nkokiki rẹ, o di ẹniti o nni ọmọ-ẹhin, o di ẹniti o nni ọrẹ kun ọrẹ ati ọta kun ọta ni Mẹka. Nigbati idamu ọta pọju ni Mẹka, ti o si ri i gbangba wipe nwọn fẹ pa on, o sa kuro ni Mẹka, o salọ si Yathreb, ti a npe ni Mẹdina tabi Mẹdinat-at-Nabi, ilu Woli, lẹhin na.

A ko ri i ka nibikibi ri wipe Muhamọdu lọ si Ṣukuru tabi Ile Keu kan, sibẹsibẹ, o wu Ọlọrun lati da a l'ọla, o wu U lati lo o gẹgẹ bi Ojiṣẹ, o wu U lati lo o gẹgẹ bi Woli Rẹ, lati gbe ogun si

fẹ̀ẹ̀rim, ati lati tubọ fi ipilẹ ẹsin Ọlọrun lelẹ larin awa ọmọ Anọbi Adamọ l'aiye.

Itumọ ẹsin Musulmi Islam ti Anọbi Muhamọdu da silẹ ni wipe, ki a tẹriba fun Ọlọrun, ki a fi gbogbo ọrọ mọ Ọlọrun l'ọkan, ki a si gba wipe, ohunkohun ti o ba ṣe ni aiye yi, ibaṣe rere tabi eyiti awa ẹda ka si buburu, a-mu-wa Ọlọrun ni gbogbo wọn.

Nibiti adun ati ẹwa ẹsin Musulumi wa pataki ni eyi wipe ki a fi gbogbo ọrọ mọ Ọlọrun l'ọkan; ati jubẹ lọ, gẹgẹ bi Musulumi, a ni lati ma gbawẹ, a ni lati ma gbadura, a ni lati ma k'irun lẹmarun lojojumọ, a ko gbọdọ mu ọti, a ko gbọdọ ta tẹtẹ a ko gbọdọ jale, a ko gbọdọ gba owo ele, a ko gbọdọ ṣe ṣina tabi agbere, a ko gbọdọ korira tabi ki a ṣe keta ọmọ ẹnikeji wa, a ko si gbọdọ huwa aiṣedede miran gbogbo.

Loni, ọkẹ aimọye enia lo ntẹle Anọbi Muhamọdu lẹhin, gẹgẹ bi ọkẹ aimọye enia bakanna ti jẹ onigbagbọ gẹgẹ bi ilana Anọbi Isa, Jesu Kristi.

Nitorina, gbogbo wa, ati Kiriyo ati Imale lo yẹ ki a jọ jumọ tẹle ilana ati ẹsin Anọbi Isa; gbogbo wa ẹwẹ, lo si yẹ ki a tun jọ jumọ ṣe asalatu fun Onişẹ nla—*Salalahu Alaihi Wasalam*.

Ẹlomiran le wipe, ipa, girimọkayi, pẹlu ida oloju meji ni Anọbi Muhamọdu, fi nmu enia ṣe Musulumi ni akọkọ bẹrẹ. K'a tilẹ wipe bẹni lati iwọn ẹgbẹfa ọdun tabi jubẹ lọ ti o ti ku nkọ o? Ṣe oku rẹ lo ji dide lati Sare, ti o nfi ida oloju meji sọ Keferi Eko di Musulumi? Ẹlomiran le wipe ẹsin gbẹfẹ ni ẹsin Imale, nwọn si ni anfani lati so yigi mẹrin ni o jẹ ki Imale pọ pupọ larin wa. Awẹ ti Imale ngba, irun nigba marun-marun ti nwọn ni lati ma ki lojojumọ, Mọṣalaşi ti nwọn ni lati ma para nigbagbogbo ati oniruru nkan miran ti Sẹria ni ki nwọn ṣe l'ọna ẹsin, idaji eyiti Kiriyo ko nṣe, ko le jẹ ki awa gbagbọ wipe ẹsin gbẹtẹ ni Imale. Ati nipasẹ ti Yigi mẹrin, awa ro pe ẹniti o ni obinrin meji tabi mẹta tabi mẹrin ti a nwi yi, ni gbangba ti o si lagbara lati tẹ wọn lọrun ni oniruru ọna gbogbo, san pupọpupọ, o san ni ọna ẹgbẹrun ju ẹniti o gbe obinrin kanşọṣo ni iyawo ti o si bura niwaju Ọlọrun ati enia wipe on nikanşọṣo ni on yio joko ti lọrun titi ọjọ iku on; lẹhinna ti o tun nle'mu kiri bi Obukọ nikọkọ ati nibaba, ti o nyan obinrin olobinrin l'ale, ti o nbimọ ti ko le jẹwọ wipe on ni baba ọmọ na, ti o nba ọmọlọmọ l'ori jẹ kiri, ti o mbere lọwọ aya alaya wipe "Nihin lo ndun ọ, tabi lọhun?" ani, ẹniti o fẹ obinrin meji si gbangba san pupọ ju ẹniti o fẹ obinrin kanşọṣo ti ọkọlobinrin miran si ra a mu lọdọ aya rẹ, ti o si mbẹbẹ wipe, "Bo mi, *and the Lord will* bo ẹ!"

Işekuşe ati agabagebe ti o wa larin Kiriyo ko si larin Imale tobẹ, sibẹsibẹ, awọn Kiriyo a ma purọ tan ara wọn jẹ wipe iwa panşaga pọju larin Imale.

Awọn obinrin onişekuşe tarata ti o wa larin Kiriyo ati Imale, awọn ti a npe ni Alada nla, tani nwọn nfi ada wọn na ṣa ju, bikoşe awọn Kiriyo apabobo afọnufọra; ti nwọn ko ri owo da ni Şọọşi, ti nwọn ko ri owo tọju iya wọn nile, ti nwọn ko ri owo d'aṣọ si ọrun ara wọn, ti nwọn ko ri owo tọju alarede ti nwọn gbe sile: loju *Sweety*, loju *Lovy*, loju Ibadi-aran, loju Awelọrun!

Bi enia ba fẹ obinrin kanşọṣo, to si joko ti i, o dara pupọ; nitori wahala kekere kọ ni o wa ninu ikobinrinjọ; şugbọn Kiriyo melo lo ha njoko ti alarede wọn nikanşọṣo nilẹ yi, l'Abẹokuta, ni Ibadan ni Ijẹbu, ati ni ilu Yoruba miran gbogbo? Apẹrẹ wo ni awọn Afa papa tilẹ nfi le 'lẹ? Ki ma şeşẹ sọ ti mẹmba; Ajọpade ha kọ ni afa miran pẹlu mẹmba njo pade ara wọn lalẹ n'ileobinrin kanna, aya alaya ti Afa ntọwọ bọ iwe fun mẹmba? Iwa aimọ, iwa amunibuni ni nwọnyi, a ko fi Kristi kọ ẹnikẹni bẹ.

Imale ko nşe ẹsin ti enia le fi ọtẹ Ilu sin, gẹgẹ bi awọn Musulumi miran ti nşe l'Eko nisisiyi; emi ko jẹ kirun lẹhin Lemọmu bayi bayi, emi olowo, emi agbalagba; tani Iwọ na. Iwọ, Iwọ to nta pa, to nfọnga si ẹniti o wu Ọlọrun, lati gbe si ipo na pe o ko jẹ kirun lẹhin rẹ. Iwọ, Iwọ ha tobi ju lati tẹle ilana Anọbi Muhamọdu pe ohunkohun ko şẹhin Ọlọrun, ati pe Amuwa Ọlọrun ni ohun gbogbo laiye ati pe Ligali to jẹ Lemomu awọn janma nisisiyi, ko şẹhin Ọlọrun.

Ki a tilẹ mu ti ẹsin kuro, Kotu Ọba King, Kotu Onidajọ kan, Kotu Onidajọ mẹta gba pe Ligali olohun iyọ ni a fi jẹ Lamọmu lọna to tọ suna; sibẹsibẹ awọn "Koşeyọ" fi ake k'ọri; anu si şe wa pe o dabi ẹnipe Ijọba papa lo nti nwọn lẹhin lati ta kanrọngbọn si idajọ Kotu ati lati da họuhọu silẹ n'ilu; bikoşe bẹ, nwọn ki ba ti fun wa laşẹ lati lọ Kirun Awẹ to kọja ni ilẹ awọn Janma. Ọdọ Ileya lo tun nbọ, şe Ijọba tun ma fun wọn laye lati tun lọ kirun lọtọ ni ilẹ awọn Janma kọ, tabi Ijọba yio duro ti idajọ Kotu? Eyiti Ijọba ba fẹ ninu mejeji, nwọn le şe; şugbọn ti Ijọba ba fi fun awọn apakeji laye lati tun lọ kirun lọtọ lodun yi, bi ija ba de, tabi asọ tabi ariwo, bi ọlọpa ba si mu ẹnikẹni, nigbana ni ao mọ wipe iwa alagbara lo l'aye Might is right ni Ijọba nhu fun wa, ati pe awọn Ijọba kanna to pe Ole wa ja lo tun pe ololo wa şọ.

Ju gbogbo rẹ lọ, nigbati a ba nri iwa miran ti ko tọ suna ti Musulumi miran nhu, ti a ba nri obinrin Musulumi to nyan Dady l'ọrẹ, ti a ba nri awọn alagidi Musulumi diẹ to nfẹ jẹ gaba lori gbogbo Musulumi iyoku n'ilu nitoripe Ijọba wa lẹhin wọn, ti a ba nri Musulumi to nfi ọti Jini gba'wẹ, ti o si nfi Wisiki sọ'nu, ti a ba nri Musulumi ti inu rẹ ndun nigbati awọn panapana nto omi si Mọşalaşi, ti a ba nri Musulumi to nba elegungun mu'ti, to nba oloriṣa j'obi, ti a ba nri

Musulumi to nta tẹtẹ, Musulumi, to nya wọn ni owo ele, ani, ti a ba nri Musulumi to nhu iwa bayi, ati iwa miran ti ko tọ suna, ero ti o nwa s'ọkan wa nipe, nibo ni nwọn ma ru u wọ lọjọ idajọ, l'ọjọ agbende alikiomọ.

Nipa adura nikan kọ ni a le fi ṣe Asalatu f'onişẹ nla, bikoşe nipa iwa wa pẹlu; nipa, titẹle gbogbo ilana Onişẹ nla papa, nipa riran ara wa lọwọ, nipa didariji ọta wa, ati lai wa işubu tabi ipalara ọmọ ẹnikeji wa.

Ko si ojulowo Musulumi kan to jẹ rena Anọbi Isa, Kiriyo ki Kiri yo to ba si ni iyemeji si Anọbi Muhanmodu ki o te ti le'lẹ ki o si gbọ ọrọ aladun Thomas Carlyle sọ nipase rẹ ninu iwe ti a npe ni "Herols and Hero Worship" o ni :—

"The word which Mahomet spoke has been the life-guidance now of a hundred and eighty millions of men these twelve hundred years. These hundred and eighty million were made by God as well as we. A greater number, of God's creatures believe in Mahome't word at this hour than to any other word whatever. Are we to suppose that it was a miserable piece of spiritual legerdemain, this which so many creatures of the Almighty have lived by and died by? I, for my part, cannot form any such supposition. I will believe most things sooner than that x x x A false man found a religion? Why, a false man cannot build a brick house. If he do not know and follow truly the properties of mortar, burnt clay and what else he works in, it is no house that he makes, but a rubbish-heap. It will not stand for twelve centuries, to lodge a hundred and eighty millions; it will fall straightaway."

A ki tẹlẹ ni a ki gbogbo Musulumi Eko ati ti idalẹ, ẹ ku ọdun, ẹ ku iyedun ki Ọlọrun şe e ni abo ọdun fun gbogbo wa. Lẹkan si i, a ke si t'ọkunrin, t'obinrin, ọmọde, agba, a ke si gbogbo ịanma pe ki a jọ jumọ şe Asalatu f'Onişẹ nla. Salalah Alaihi Wasalamu.

Emi ni ti nyin nitotọ,
ATARI AJANAKU.

---

## OLUSAKIN'S COLUMN.

### Notable Incident at St. Paul's Church.

PREACHER'S FEATHERED VISITOR.

There was something of a sensation last evening at St. Paul's Breadfruit Church during the Lenten Service when at the height of an absorbing sermon by the Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi, a bird dashed through one of the southern windows into the Church and perched on the pulpit, before the preacher. The feathered creature remained there for a few minutes then flew away again to a corner of the Church where it was captured by one of the senior sidesmen, Mr. D. A. Bright.

A great section of the more superstitious of the congregation attach great significance to the incident and regard it as some Omen.

The Archdeacon text was taken from Zechariah 7. 11— "But they refused to hearken and pulled away their shoulders and stopped their ears that they may not hear." He was expatiating on the observance of fasting during Lent season and the futility of fasting unaccompanied by good works, when the feathered visitor arrived at the Church.

The bird is of the ordinary local finch variety.—*The Nigerian Daily Times, 15/3/28.*

We learn that the bird in question is still with Mr. D. A. Bright.

### Births.

We congratulate Mrs. Yewande George, wife of Mr. Charles William Regmund George, Street Inspector, for the safe delivery of a Baby boy on Thursday, the 8th March, 1928. The mother and its child are doing well

---

Mrs. Stella Kayinu, wife of Mr. E. I. Kuyinu of the Nigerian Railway Traffic Audit, Ebute Mẹta, of a son on Tuesday the 13th March, 1928. It is reported that both mother and child are doing well. Congrat.

---

Madam Florence Shanu was delivered of a male child at Ebute Mẹta on Friday the 16th instant, both mother and its child are reported to be doing well. Congratulation.

### Mr. D. O. Sowande.

Having spent six weeks out of his 2 months' leave at Abeokuta, Mr. D. O. Ṣowande, President Judge, Ake Court, Grade A, arrived Lagos on Saturday the 17th instant, to spend the remaining two weeks before resuming his duties at Abeokuta. Alafia kọ lẹ de bi ?

### Arrival.

We welcome Mrs. Comfort Thompson, wife of Mr. J. G. Thompson of the Elder Dempter Line, who arrived Lagos from Abeokuta, on Saturday, the 17th instant, whither she had gone on health trip.

### Departure.

By the steamer *R M M L. Aba*, which sailed this port on Friday the 23rd March, 1928, Mr. Ernest Christian Nelson Scott, African Assistant Accountant, Nigerian Railway Accounts Department, Ebute Mẹta, who is on 4½ months' leave, was among the passengers to Freetown, Sierra Leone, with Mrs. Scott. Bon Voyage.

### On Leave.

Mr. J. L. Oni, 1st Class Senior Compositor, Railway Press, Ebute Meta, is on 2 months' leave, as from the 19th March, 1928. Mr. Oni hopes to visit Kano and Port Harcourt.

### Retirement of Mr. Sydney Fairman.

In honour of Mr. Sydney Fairman, Storekeeper, Nigerian Railway Stores Department, Ebute Meta, a Farewell Party was given at Goldstone House, the Fields, by the Hon. Kitoyi Ajasa and Mrs. Ajasa, on Saturday afternoon, the 17th instant.

---

Another function in honour of Mr. S. Fairman, a Farewell Reception at the Railway African Staff Tennis Club Grounds, Ondo Street, Ebute Meta, took place on Tuesday afternoon, the 20th instant, at 5 p.m. Among those present being Mr. & Mrs. A. H. Bridgman, Chie f

Storekeeper, Mr. & Mrs. C W. Wakeman, Mr. A. Wilde, Mr. S. C. Griffiths, Mr. & Mrs. A. E. Westlake, Dr. R Akinwande Savage, Messrs. C. W. Faulkner-Shaw, N. F. Williams, J. D. Akibanmi, A. S. Coker, J. H. Glover-Willoughby, A. J. Marinho, Jnr., Owolabi Ebinisi, O. O. Akiyemi ( of Ireṣa ) Mr. & Mrs. D. A. Bright, O. Eṣuronbi Aro, L. O. Thompson, D. T. Abraham, Pope Pious John, E. E. Johnson, D. O. Olubi, E. A. Davies, D. A. [illegible]assey, E. A. Alade, M. O. Denloye, J. O. Adeusi, S. T. Odunsi, E. A. Shiwoku, Y. Aziz, Mrs. E. B. Ogunmẹfun Mr. & Mrs. W. C. Gulin, Prince Odẹdina and others.

An inscription was read by the Secretary Mr. Ọlamide Ajayi, followed by the gift presented by the Staff through Mrs. W. C. Gulin in appreciation of Mr. Fairman's tact, honourable and faithful services rendered to the Stores Department for 15 years and consideration for all the African Staff who came in contact with him.

Mr. Fairman then thanked the Staff for the good wishes they maintained towards him, and also thanked the Ladies and Gentlemen for their presence.

Mr. Bridgman, the Chief Storekeeper, expressed his greetings to the Staff and commended Mr. Fairman's service in the Stores Department. The gathering was brought to a close at about 7.20 p.m.

We congratulate the Chairman Mr. S. O. Ajayi, Mr. Ọlamide Ajayi, the Secretary and all concerned.

### Mr. Oke Adeshigbin.

Mr. Oke Adeshigbin (alias Major) left Lagos on Wednesday the 21st March, 1928, for Oshogbo. Mr. Adeshigbin hopes to visit Ile Isha and Ile Ifẹ as well.

OLUṢAKIN.

---

Si Oni'we irohin "Eko Akete."

Kabiyesi o,

Ni lailai nigbati awọn Alaṣẹ wa ba gbe ofin to ma ni ilu lara ju silẹ fun wa, gbogbo wa t'ọkọnrin t'obinrin, ọmọde ati agba, a dide pẹlu ariwo, a fi ori le ile Gomina, a o gba, awa ko gba o, ariwo a gba ilu kan, ilu a daru, ṣugbọn loni, ọpẹ ni fun Ọlọrun, ẹniti o fun wa ni oye lati mọ pe ko si rere ninu iru iwa bẹ, ẹlomiran le ro pe ṣe 'tori Panapana ni a ko ṣe le hu iru iwa bẹ mọ, bi a ba ri ẹniti iru ero bẹ wa lokan ẹ, ọpe enia patapata ni oluwarẹ, ko dede Panapana ha ju Ọlọpa lọ tabi Panapana ju Ṣọ a ( *Soldiers* ) lọ ni, ọgbọn lo tubọ ga si la ba mọ pe tabi la fi ka iru iwa bẹ si ere ọmọde.

### IWE IROHIN.

Iwe-irohin jẹ amọna tabi atọnisọna fun enia kan, fun agbo'le, fun ilu, papa fun awọn Alaṣẹ wa, ni.orina a bẹ awọn Alaṣẹ wa pe nigbakugba ti iwe-irohin kan ba nfi ẹdun ọkan ilu han, o tọ o si yẹ ki awọn alagbara wa joko ki nwọn ṣe aṣaro ijinlẹ lori ọrọ na, ki nwọn to mọ iru ohun to yẹ ki nwọn ṣe pẹlu wa.

---

Iṣe Ara ko jọ iṣe Igede, bi obinrin wọn ba ku l'Ara, nwọn a pejọ, nwọn a fẹ omiran fun ọkọ ẹ, ṣugbọn bi obinrin wọn ba ku ni Igede, nwọn a pejọ nwọn a le ọkọ ẹ lọ. To to o.

Ẹnito gbẹ'lẹ lo sinku, ẹnito nsunkun ariwo lo npa. Owe ni o.

'Lori owe yi la fẹ bẹrẹ ọrọ wa.

KOṢẸHIN ỌLỌRUN.

---


## Sale by Public Auction.

One of the largest compounds in Lagos, containing several decent houses situate at 157, Bamgbose Street, Brazilian District, Lagos, to be sold on Tuesday at 4.30 o'clock p.m. on the spot.

OLABOYE LALEYE,
*Licensed Auctioneer,*
33, Alli Street,
Lagos.


---


## INA WỌ'LE OKUNKUN PARADA



Atupa ti a npe ni "Oṣupa mi" jẹ oju lowo ati papin atupa hanun ti o si yẹ ilekile, papa ile awọn gbajumọ olowo, a ko le ṣẹ ma sọ ti awọn "Dẹngẹ". Agbara rẹ pẹlu agbara atanpọ ọdunrun abẹla, dede ni, bi ọsan si ni titan rẹ ri ninu ile. Agba ti koi ti lowo gbigba Atupa Ṣango sile ki o ma jafara lati ra atupa meremere yi ti o na electric jẹ.

Oriṣi meji lo wa fun tita: ti oni-fadaka ati ti onidẹ.

Ẹ lọ yan ti nyin ni Ṣabu Oyinbo KESSLER ni No. 7, Labinjọ Lane.

Ẹnyin ara-oke ati ilu miran, ẹ mase gbẹhin ki ẹ to ranṣẹ ti nyin, ki ẹ ma ba j'oku ologbo.

# NOTHING BUT TRUTH.

## Banish away your rheumatism by using

## "WALK EASY ANTI-RHEUMATIC SALTS"

(EGBOGI LAKUREGBE AJẸ-BI-IDAN)

Sold only by:—

***K. B. SAVAGE,***

IYIN OLUWA MEDICINE STORE,

88, Broad Street, Lagos.

---

**VIBRONA**

**VIBRONA**

**VIBRONA**

# WINE

**Refreshes the strong**

**Restores the weak**

**Revives the depressed.**

**The Highest Medical Authorities say so!**

Local Representative:—

***K. B. SAVAGE, Esq.***

*Head Office*:—88, Broad Street,

*Branches at*:—6, Martins Street,

41, Alli Street, Faji Market,

109, Griffith Street, Ebute-Metta.

## White's Golden Male Tonic

DOUBLE STRENGTH ).

Whenver a woman has not been in the family way for a long time, the fault is usually set down to some disease or other in her generative organs. Now while it is true that many women suffer from disease, yet many times the fault lies with the man, owing to weakness or some other disease of the male organs of generation. White's Golden Male Tonic (Double-Strength) is calculated to give full vigour to the man, and to remove all diseases which prevent breeding. Every sensible man ought to use two bottles every month, to cure or prevent weakness of the generative organs.

Made and sold only by VICTOR WHITE, Esq.,
*The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos*
*N.B.*—NOT OBTAINABLE ELSEWHERE.
"Shake the Bottle."

### RẸMỌ FUN ỌKUNRIN.

Nigbati obinrin ko ba tete loyun, a ma nro pe ara obinrin na nikan ni arun wa. Ṣugbọn nigba pupọ ni o nję pe ara ọkunrin ni arun wa. Egbogi yi dara pupọ fun Arę, Ẹda ati gbogbo arun ti ki ę ki ọkunrin ṣe abiamọ.

*N.B.*—O yę ki gbogbo ọkunrin ma lo igo meji-meji loṣoṣu—Iṣę ti egbogi na nṣe ni ara ko ṣe royin.

Price TEN SHILLINGS ( 10s ) per bottle.

*Postage 2/6 extra.*

## White's Golden Female Tonic.

A splended Remedy for Female diseases such as :—Barrenness, Weakness, Painfull and Irregular, Menstruation Leucorrhœa (Whites) Cramps, Ovarian, Neuralgia, Inflammation of the Ovaries. A Tendency to Miscarriage etc, etc.

Made and sold only by VICTOR WHITE Esq.
41, Offin Road, Lagos.
*N.B :—Not obtainable elsewhere.*

### GBOGBONIṢE FUN OBINRIN.

Egbogi yi dara pupo fun Al oyun, Iju, Ẹda, Aran, Oyun ti o ba fę baję, ati orişirişi arun mi ti ki ję ki obinrin bimọ.

PRICE 10/- PER BOTTLE.
**Postage 2/6 extra.**

WHITE'S
## WONDERFUL BRAIN TONIC

This medicine stimulates and rebuilds the brain in such a way, that the regular user is able to do many times the usual amount of Brainwork that he used to do, before using it. To Brainworkers and those who have examinations to pass, it is a boon.

Made and sold only by SAMUEL VICTOR WHITE, Esq
41, OFFIN ROAD, LAGOS.

Large size 5/- per bottle. Packing and Postage 2/6 extra.
Small size, 2/6 per bottle. Packing and Postage 1/6 extra.

N.B.—*Scholars should not be without it.*

### EGBOGI ISỌYE.

Egbogi yi dara pupọ fun awọn ọmọ-ile-iwe awọn ti o nṅ iwe şişę ati gbogbo awọn ti o ba ni lati lọ fun idanwo.

*Iba şe ọmọde tabi agbalagba.*

## White's Golden Blood Restorer

*( A Native preparation for Women.)*

This medicine is an excellent remedy of Insufficiency or Loss of the monthly courses, Tumour in the Womb, False Pregnancy, Catarrh of the Womb, Various Runnings or Morbid Discharges from the Womb ( especially those that are long-standing ).

Sick Headaches, Dizziness, etc., etc.

Made and sold only by
VICTOR WHITE, ESQ., *Chemist,*
The Reliable Dispensary, 41, Offin Road, Lagos
"SHAKE THE BOTTLE".

Price TEN SHILLINGS ( 10/- ) per bottle.

*Packing and Postage 2/6 extra, to any part of Nigeria.*

### EGBOGI ILANA ẸJẸ FUN OBINRIN

Egbogi yi dara pupo fun obinrin ti ko ba ri nkan oşu rę mọ ( lalai to aşeko ). nkan obinrin ti ko ba pọ to. Aşę Ewurę pipọju, Ẹda ti o ba gbe Ẹyo, Oyun-koyun. Oyun ti ko ba dagba, Oju Ẹsanri ni akoko hela, Aran ati iju.

## HORSFIELD'S

The well known suppliers of all classes of goods under the registered Trade "ZODIAC" Mark.

Call and see our Agent and give your orders to:—

MR. MOSES O. COKER,

Port Novo Market Street, Lagos.

who has samples every mail of all the latest styles of fancy and other goods, including our REGISTERED Palm Tree and Feather Embroideries.

We supply everything.

J. J. HORSFIELD & CO.,
(Manchester) Limited,
65, George Street,
Manchester.

GOOD MARKET.

Gonorrhea Specific, Moloke Mone, A. & D. Bula Matadi for health-restoring purposes: these Medicines are on sale at Mr. H. Campos's First Class Shop, 37, Odunlami Street, Lagos. The Specifie acts like Magic: has cured many obstinate cases, and *will cure yours just the same*, if any.

Cheap Goods! Superior Quality!! Quick Fortune!!!

*Cable Address*:—"WHITE LAGOS".

MR J. T. AKIREMI WHITE
P.O. Box 82
20, Balogun & Breadfruit Streets
or
41, Offin Road, Lagos.

**Indents House.**

Import of General Lines
Export of Produce Commission Agencies undetaken.

Correspondence invited.

With over 22 years' experience in this line of business.

Mr. White's well-known connexion with reliable Firms in Europe is a matter of common knowledge to his clients.

A Trial is Solicited.


When replying advertisers please mention *Eko Akete*


**TO LET.**

**One Splendid Pleasure Car**

No. L2754.

**Always at everybody's service at Tinubu Square.**

For Terms, Apply to:—

A. B. Williams,
14, Bishop Street, Lagos.

# ILE OWO OYINBO

# JOHN RADCLIFFE

## Ni No. 63, Ehingbeti, Eko.

———:o:———

Ile-owo ti o wuyi fun ọja meremere bi Ṣẹda, aṣọ Yọmi.. ati aṣọ ti a fi ẹlẹya Oyinbo gbaleti.

Ẹ wa bẹ orişirişi ọja wa wo ni Ile-owo wa titun to kọju si Ile Niger ni No. 63, Ẹhingbẹti.

Aṣọ lorişirişi ni aṣetejọ: aṣọ Ṣẹda ati Siliki mbẹ bi aba, awọn wọnyi jẹ eyiti awọn onibara ṣa ti nwọn si ti sami si fun ra wọn. Aṣọ lami-titi ti a npe ni Ṣantọnu nkọlu 'ra wọn.

Agbalẹtu ni gbogbo ọja wa fun didara wọn.

Pọ ọ si ni owo wọn.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING PRESS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.